**Asayan Oro**

Ewure wo alapata, bi ki o ku. Awodi wo igbin koro. Kini eiye oko yio fi igbin se ? Ori l'o nise eda l'a yanmo.


# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO


**Akiyesi Pataki**

A fiwe yi s e ikede si awon Asoju Iwe irohin Eleti Ofe kakiri agbaiye wipe enikeni ti ko ba fi owo ti o ti je ranse si wa, a o pe lejo, ako si ni fi iwe irohin ranse si enibe mo.


VOL. XI No. 644. LAGOS. SATURDAY, OCTOBER 10 — OCTOBER 16, 1959. KOBO MEJI (2d)


# Ekunwo De Fun Awon Osise Jake-jado Ile Nigeria

EK . Irohin ati okiki ekunwo ti Ijoba apapo le se ati Ijoba Ariwa pelu ti Ila-orun fun awon osise abe won ki abo iwadi ti awon yan to yori wipe ki o le je idekun ati irora fun awon enia osise na, ninu eyiti Ijoba Iwo-orun wipe "Oto ni Segede nda'gba tire" ti Ijoba Iwo-orun na si tun se ekunwo ti won bakanna fun awon osise enia abe won.

Gegebi a ti gbo eto ekunwo na si nipe Ijoba Apapo ati Ijoba Ariwa pelu Ijoba Ila-orun yio san sile meji (10 percent interim) lori ponun kokan owo ti awon osise ngba fun won ki abo iwadi iye ti o to ki a fi kun owo osise to jade.

Sisan owo na yio bere lati ojo kini osu September 1959.

Sugbon Ijoba Iwo-orun yio bere sisan ti won lati ojo kini osu April, 1959. Iyen ni wipe ekun owo na yio san die fun awon Osise Iwo-orun ju ti awon ipinle meteta yoku lo. Sile meji (10 percent interim) lori ponun kokan bakanna ni o.

Nigbati abo iwadi ti awon Ijoba Apapo, ati Ijoba Ariwa pelu Ijoba Ila-orun ba jade, bi o ba ni eto lati fikun owo awon osise ju be lo, awon yio se atunse re fun won, bakanna ni Ijoba Iwo-orun yio se atunseti won na ti abayori iwadi ti awon nse ba jade.


## Lagos Race Club

### Governor General's Cup

### Sweepstake

Ticket books for the above Sweepstake for Christmas 1959 can now be obtained on application to the Secretary, P. O. Box 51, Lagos or at the Race Course.

**These tickets are 2/6 each.**


## Ola Ngori Ola



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye S.I. Edu, ti o je okan pataki ninu awon olugbimo Iwo-orun, ni a gbo wipe o tun wo igbimo awon Oloko oju omi, o ti wa ninu igbimo awon Oloko Ofurufu.

Iyen wu wa o, Oloye Olola S.I. Edu nwa.

## OLE TO JI SIGA LO S'EWON

IBADAN Omokunrin kan ti awon npe ni Akilapa ni awon olopa ramu fun esun ole siga ti o ji lodo obinrin kan ti awon pe ni Sifawu Alari ti o ngbe Oke Bola ni Ibadan.

Odaran na so wipe obinrin ti awon ni, Sifawu Alari je ale on nigba gbo gbo lo si ma nwa san nanu vara on ngbe ti oko re ko ba si nile, o to igba meji ti o se be.

Ejo ti awon Olopa mba Akilapa ro ni wipe o ji pali siga Gallons meji, eyiti owo re je sile meta abo lodo Sifawu laisi imo Sifawu nibe.

Sifawu so fun adajo wipe ko si otito kan ninu gbogbo oro ti Akilapa so ati wipe on ko mo o ri, ohun kan ko si pa ti on tire po ri.

Adajo so pe ejo Akilapa arufin yi jebi nitorina ki o yara lo gbewa osu mefa.

## IDIBO IGBIMO IBILE ILU ILORIN

**O ta siwa leti feuren wipe ibo ti awon di nilu Ilorin, awon egbe Olomi (N P C) ni o bori ninu idibo na.**

Gegebi a ti gbo aye idibo na si ni pe egbe Talaka Parapo ti o jo alabasepo pelu egbe Afenifere (A. G.) ni enia enia metala, a si gbo wipe (N. P. C.) egbe Olomi ni enia mokanlelogun. Egbe Olomi (N.P.C.) lo bori o.

## Okunrin Kan Fe Pokunso

KADUNA Okunrin kan ti oruko re nje Joseph Okioya, lo jewo riwaju adajo wipe on momo kowe si iyawo on wipe on wipe bi ko ba fi on sile jeje, on yio pokunso nitori owo onje ti awon ma mbere lowo on lojojumo ti oro na si ma ndi ija.

Awon olopa so wipe, nigbati okunrin na kowe si iyawo re tekere o wipe gbogbo nyin lo mo pe, emi ko ni ise se ojojumo ni oro owo onje ndaja sile larin emi pelu nyin. Oro na de gongo, o tile su mi, emi felo pokunso nitori nyin. Ejo na si wa ni kotu, kotu pari.

# Idubor Nilu Oyinbo



Enia a nwo ti o wo ewu agbada ti o duro larin awon Oyinbo meji ni omokunrin kan ara ile Benin ti oruko re nje Idubor ti o nse ise agbegilere, on ni awon oyinbo ti o duro egbe ati lori mbere oro lowo re.

## Oro Ilu Kamerum Gba Ibo Didi

Bi oro ile Kamerun ti nlo yi, ko yeni si. Nigbati Dr E.M.L. Endeley nse Asiwaju awon Oselu (Premier) gbogbo ero re ni lati pa ile Kamerun po mo ile Nigeria. Nigbati igba na si tun yi pada ti ipo asiwaju awon Oselu tun bo si owo ogbeni John Fonsa, on lo so wipe, awon ko le wa ni ipapo pelu Nigeria ayafi Kamerun ti Faranse, gedegbe ni awon fe ki ijoba won je kuro lara Nigeria.

Ogbeni John Fonsa ni Olotu Ijoba ile Kamerun nisisyi, on ni alase, Dr Endeley ni alatako ijoba, nibiti awon mejeji nwonyi gbe nfa oro yi mo ara won lowo, Gesi ko kuku gbodo da si nitoripe alagba toju ni awon je, nigbana ni awon to to oro na ni siso ba ranse si won, eyi ni egbe Majeobaje (U.N.O).

Nigbati nwon nlo, John Fonsa lo Dr Endeley lo, Asoju Gesi lo. Nigbati won de ohun, Fonsa so pe Ijoba ti on ko ni papo pelu Nigeria, ayafi Faranse bikose be gedegbe ni ijoba on y i o w a. Dr Endeley dahun wipe bi ilu Kamerun ba duro gedegbe ti ko faramo ile Nigeria, babanla iya yio je ara ile Kamarun Asoju Gesi ti o ba won lo so wipe Ijoba Kamarun ko lowo lowo, bi nwon ba ya kuro lara ile Nigeria nwon o di talosi, bi o tile je wipe nwon ni nkan ti nwon le fi sowo lowo Nigeria lo le pate oja won. Ni nwon ba pada wa sile laifi ori oro na ti sibikan.

Biri, biri, biri Oro ti Dr Endeley ati ti Fonsa ti wo inu ara won wipe gedegbe ni awon t e i l e Kamarun. Iyalenu lo je fun asoju Gesi wipe o r o Fonsa ati alatako re de ti wo ara won. Nigbana ni on na wa taku wipe, awon ara ilu Kamarun ko fe ya kuro lara ile Nigeria, bi beko, e jeki a dibo fun gbogbo enia ki a le mo iye enia ti o fe Nigeria tabi gedegbe.

## AISUN OKU ABISOGUN KAMAMA, ISINKU RE LARINRIN.

EKO. "Ni ale ojo Monday mojo Tuesday ti ise ojo 5th osu October 1959 si ojo 6th nigbati nwon nse aisun oku Oloye Asingbon Akinbunde Abisogun ti o jalaisi ninu ile re ni opopo Oshodi, ni Epetedo ni Eko, ko se fenu so tan.

A ti ri orisirisi aisun oku nilu Eko, okan ni ti Abisogun yi je. Awon alawo Opa wa sibe, Awo Akaja wa be, Awo Erikina wa be, Awo Osugbo wa be, Adamu-orisa wa, eyiti Ologbe na je Olori ati Oloye alase pataki ni di Eyo Adamu Orisa ti ko je ki a mo awon elere onilu dundun, aro ati S e k e r e.

Awon alagemo fi ere Agemo dabira nibi aisun oku yi, beni awon Eyo su yo nigbati o di ojin dundun ki o ma wa wo bi awon eyo ti njo bi alarakumapala

Ogbeni Akintunde Abisogun, ti ku lati ojo 1st osu October 1959, ki a to wa sin oku re ni agogo merin irole ojo 6th osu October, ni ite oku Ikoyi lehin isin ikehin ni Sosi alagogo (Christ Church Cathedral) ni Elinigbeti ni Eko.

Awon enia pataki-pataki ati awon ijoye enia lokunrin labinrin lo peju-pese sibi oku na. Oloye Sir Kofo Abayomi, Adajo G. B. A. Coker ati olori awon olopa Ogbeni A. S. Agbabiaka, Dr. Abiola A k e r e l e, Councilor Taju Thompson, Oloye S. L. Edu, ati awon jankanjakan be be ni nwon s'oju s'ehin nibi oku na.





PHILIPS

'West African' RECORDS

Wholesale Distributors:

Badejo Stores, 5 Olorogun St., Lagos
Dayo Development Co., 161 Victoria St., Lagos
Josy Ola Fajumolu & Bros., 21 Balogun St. West, Lagos
Nwosu Bros. Stores, 24 Asa Rd., Aba
Ebele Egbunam Stores, 38 Church Road, Kano
Olasinbo Business Enterprise, P.O. Box 53, Kano
Ezenweaku Trading Stores, 48 Aggrey Road, Port Harcourt

PHILIPS (W.A.) LTD. P.M.B. 2023 Lagos





## Arewa Meji Pade Arawon



Awon enia meji ti a nwo ninu aworan yi ni awon arewa meji Miss Ghana ati Miss Britain.

No. 137

## 1959 Christmas Mails For Abroad Latest Dates Of Posting At Lagos

The Posts & Telegraphs Division of the Ministry of Communications & Aviation has announced the latest dates of posting at Lagos of this year's Christmas Mails going outside Nigeria. While the Division has taken every reasonable precaution in the compilation of the posting dates no liability will be accepted in the event of an item failing to arrive at its destination by December 25. Information concerning countries not listed below and the latest dates of posting at places in Nigeria other than Lagos can be obtained from the local Post Offices.

The following are the latest dates for posting at Lagos:

| DESTINATION | AIR | SURFACE | |
|---|---|---|---|
| | | Letters and Packets | Parcels |
| Australia | 7 Dec | 18 Oct | 18 Oct |
| Belgian Congo | 14 Dec | 18 Oct | 18 Oct |
| Canada | 8 Dec | 1 Nov | [illegible] |
| Ceylon | 10 Dec | [illegible] Oct | [illegible] |
| Dahomey | 17 Dec | [illegible] Nov | [illegible] Nov |
| Europe (Continent of) | 13 Dec | 15 Nov | [illegible] Nov |
| French Cameroons | 16 Dec | 15 Nov | [illegible] Nov |
| French Equatorial Africa | 16 Dec | 18 Nov | 18 Nov |
| Gambia | 17 Dec | 29 Nov | 15 Nov |
| Ghana | 16 Dec | [illegible] Nov | 21 Nov |
| India | 15 Dec | 18 Oct | [illegible] Nov |
| Israel | 12 Dec | 1 Nov | 15 Oct |
| Ivory Coast | 17 Dec | 19 Nov | 1 Nov |
| Jamaica | 10 Dec | 31 Nov | 19 Nov |
| Japan | 7 Dec | 10 Oct | 11 Nov |
| Kenya and Uganda Tanganyika | 9 Dec | 18 Oct | 18 Oct |
| Lebanon | 12 Dec | 1 Nov | 18 Oct |
| Liberia | 17 Dec | 18 Oct | 1 Nov |
| Malaya | 11 Dec | 18 Oct | 18 Oct |
| New Zealand | 5 Dec | 18 Oct | 18 Oct |
| Pakistan | 13 Dec | 18 Oct | 18 Oct |
| Rhodesia and Nyasaland Federation) | 18 Dec | 1 Nov | 18 Oct |
| Senegal | 17 Dec | 1 Nov | 18 Oct |
| Sierra Leone | 17 Dec | 1 Nov | 18 Oct |
| South Africa | 10 Dec | 18 Oct | 18 Oct |
| South America | 11 Dec | 18 Oct | 18 Oct |
| Syria | 12 Dec | 1 Nov | 18 Oct |
| Trinidad | 10 Dec | 1 Nov | 1 Nov |
| United Kingdom | 16 Dec | 29 Nov | 29 Nov |
| U. S. A. | 11 Dec | 1 Nov | 18 Oct |

**APPROVED**

Permanent Secretary
Ministry of Communication & Aviations Lagos.

## ARCHBISHOP AGUDA DI ENI ADORIN ODUN

**Eni-owo, ọlọlajulọ Alufa Dr. Leo Taylor, ti o jẹ Olori Alufa fun ijọ Aguda, ni ogunlọjọ awọn ijimi enia ninu ijọ won se isin** Holy Cross Cathedral ni ilu Eko fun ajodun adorin ọdun ti a bi sile aiye.

Lojọ ajodun na, Olori-alufa na wọ aṣọ oye rẹ nla, awon akọrin nkọ orin bi o ti ngbe ẹsẹ lọkọkan. Ile isin kun, ọna bo fun awon alabaṣe. Bishop J. K. Aggey lo ṣe eto isin na.

Alufa to ṣe wasu ni Eniọwọ J. A Adeneyẹ, o si pe ọlọjọ ibi na ni Baba, Aṣiwaju, Ọrẹ ọmọ akẹkọ, Oloye ati woli alara mimọ.

Ninu ase nla ti nwon pe ni Mainland Hotel fun Dr. Leo Taylor si, o de ibi ase na pelu ara lile, gere ti o si de ibẹ tan lo bere irisan. awon ti ni lati tete mu yera kuro nibẹ, o si ti ri alafia nisisiyi.


E MA KA
IWE IROHIN
ELETI-OFE
LỌSỌSẸ
O KUN FUN
IROHIN ALADUN

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ŞE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS  CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos.  "ELETI - OFE LAGOS"
P. O Box 468  Phone 23370

VOL. XI NO. 644 SATURDAY OCT. 10 - OCT. 16 1959


# Ma Fo'run Yo Mi...

Gbogbo wa l'o nlọ ko si ẹniti ko ni ku laiye, iku pa Babalawo bi ẹniti ko gbọ Ifa, iku pa Oniṣegun bi ẹniti ko gb'ogun, iku pa Alufa bi ẹniti ko nke pe Ọlọrun.

Olowo nku, gbajumọ nku, talaka ti o jẹ mẹkunnu ẹnia nku, ọmọde nku, agbalagba nku, awaiye aiku ko si, gbogbo wa ni yio lọ jihin iwa wa, iṣe wa ati ilosi wa si ọmọ enia lode aiye fun Ọba Olodumare, Ẹlẹda gbogbo wa.

Nitorina iwa l'oju, ki olukuluku tọju iwa rẹ, iwa ni yio ṣe ẹlegbe lẹhin ọmọ enia lọjọ ajinde.

Kia maṣe gbagbe ọrọ orin ti Ọgbẹni Bẹgbaji, olorin Eko aiye rere ijọun, ti o kọ bayi:-

Awọn to kọro Ọlọrun, Lọtẹ Anọbi Noa. Nwọn ti ba omi lọ. Firiaona to ṣọtẹ, To ba Anabi Musa leri, Iku omi l'o ba lọ. Mẹdogun l'esu Anabi Yisa, Oban l'onigbagbọ bẹru, ti nwọn pe Ọlọrun logo Oba wọn, Ẹnyin ti ẹ ke 'ọgọta, oro aiye. Ti ẹ ko tẹle t'Anabi kan, Igi ma da, bi a ba de ọdọ Ọlọrun.

Ọrọ re o, ẹnyin ara wa.




## Igbakeji Akowe Agba Nilu Oyinbo



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni Sir Hilton Peynton K.C.MG. o di eni ọdun mẹrinle-ladọta. O bẹrẹ iṣẹ oba ni ọdun 1927 nibiti nwọn nkọ ọgbọn ori. Ni ọdun 1929 ni wọn gbe kuro nibe lo sile iṣẹ ijọba lọdun 1941 si 43 o nṣe akọwe Lord Beaverbrook, o tun ṣe akọwe Oliver Lyttleton. On lo gba ipo John Macpherson ninu iṣe oba nigbati o lo joye Gomina ile Nigeria.

## JẸKI AWỌN ỌLỌPA ŞI ŞẸ WỌN LAIŞẸGBE

KADUNA Alhaji Sir Ahmadu Bello, aṣwaju awon Oṣelu ni Oke-Ọya lo mba awon ọlọpa ti Ijọba ibilẹ Hausa sọrọ wipe ki olukuluku awon ọlọpa se ise won laiberu ati laiṣegbe.

Nitoripe, bi ẹ ba ngbọ gbe, gbe, gbe bi e jko ba si tete ba won gbe, ẹhunkule oluwarẹ ni nwon o gbe ju si. Nitorina bi akoko ti nyi pada bena ni ki awon ma te siwaju pẹlu rẹ.

Awon akan ti ko jẹlẹ ri, ni a ri ti o si ụṣẹlẹ nisisiyi. O ni ọdun mẹrindinlogun ni on fi ṣe itọju awon ọlọpa ni Şokoto eyi lo lẹ je ki on mọ diẹ nipa iṣẹ won.

Ninu opolọpọ irin ti on ti ri nipa awon ọlọpa, on ṣakiyesi pe awon ọlọpa ijọba ibilẹ ngbe ẹsẹ kan na papọ pẹlu awon Nigeria Police. Ki ẹ tunbọ ma te siwaju ninu iṣẹ ati iṣe nyin, ki awon ara oke na ma ṣe le yin, eebu si wa lara.

## ỌWỌ TẸ ARUFIN TO SA

EKO. Irohin kan wa wipe, ọmọkunrin kan ti o njẹ Dalẹ ni awon ọlọpa ranṣẹ fun ẹsun wipe o fọle onile, o si ji won ni ẹru kolọ.

Nigbati adajọ yẹ ẹjọ na wo, ọdaran na ni on ko jẹbi, ẹni adajọ ba yẹ ẹjọ rẹ sigba miran, o si gba iduro fun ọdaran na. Ni igbati akoko ẹjọ rẹ to lati wa so ti ẹnu rẹ, Adajọ ko ri Dalẹ mọ. Nibiti awon Ọlọpa gbe nwa kakiri ti nwon ko ri ni nwon ba lọ mu ẹniti o duro fun lọ si itimọle ni ẹgba ẹwọn.

Ko pẹ lẹhin eleyi ni awon ọlọpa ilẹ Ghana ranṣẹ de, wipe ọwọ tẹ ọkunrin na ti nwon npe ni Dalẹ lohun, o si mbẹ ni itimọle. Awon ọlọpa Eko nṣe eto lọwọ lati lọ mu Dalẹ bọ wa silu Eko.


E MA KA

IWE IROHIN

ELETI-OFE

LỌSỌSẸ

O KUN FUN

IROHIN ALADUN

# Obinrin Kan Sin Gbese Yo S'orun

BENIN. Ọkunrin Isobo kan nrojọ fun awọn Ọlọpa, o sọ wipe, Obinrin abilẹkọ ti o ku na, nitotọ ni on ti jẹ ni gbese pọun kan, ṣugbọn on ti san owo na fun u pada.

Iyalẹnu ni ọrọ na jẹ fun on nigbati on nlọ si oko, ti obinrin na tun wa sin on ni owo ti on ti san fun ibẹ ni mu ti bi on, tiẹon, la ada yọ ni on ba sa a ni ọgba meta ni atari rẹ.

Adajọ bere wipe, ṣe iba owo ti o sin ọ nigbese rẹ na lo jẹki o pa a danu? Ọdaran na dahun wipe, nigbati o mọ pe mo ti sanwo fun u fun ki o lo se tun nsin mi ni owo on lo fe parare, ni adajọ ba yẹ ẹjọ rẹ sigba miran.



We build complete liquid fuel storage plants with all required auxiliaries and supervise assembly works.

We supply tanks: horizontal non-pressure and pressure tanks with capacities up to 100 cu.m. Vertical non-pressure tanks capacities up to 10.000 cu.m. with complete auxiliaries.

Made according to Swedish/API — STD 12 — September 1955 Svenske Cisternormer 1,2 edition 1956/and German/DIN 4119/Standards.

CEKOP

Exporter of Plant Equipment and Complete Works
Warszawa. Mokotowska 49. Poland
P.O. Box 112
Cable address: Cekop Warszawa

## Erin Wo Sosi Lakoko Ti Nwon Nse Isin

ITALY. A gbo irohin wipe lasiko ti awon ijo Aguda ti o wa nilu Milan nṣe isin iranti Ologbe Saint Francis alara mimo ti o fẹran awon eranko, beni abo erin nla ti awon pe ni Mary nkoja lo.

Moto kan wa nsare bo lẹhin erin na lati gba iwaju re, ṣugbọn o ṣe Kere siwaju bẹni moto na duro fun lojiji ki o le koja.

Ariwo dẹduro ti moto na la lauresi mo ti o duro, ariwo ti moto na pa derùba erin na. O sare bẹ sinu ogba Ṣọṣi, o fẹ gba oju ferese wole lasiko ti nwon kunlẹ ti nwon ngbadura lowo, o di bi o ko lo yago fun mi.

Gbogbo enia ngba oju ferese ati ona Alufa sa jade Erin na ti ko owo iwaju wole sinu Ṣọṣi o wa ku ese ehin nita ibẹ lo wa ti gbogbo Ṣọṣi fi tuka

## Warapa Gbe Eni-kan Ninu Moto Akero

EKO. Irohin ko to afojuba ni ojo 5th osu October 1959 nigbati moto Akero (Bos) kan mbo wa si Eko lati ona oke, 'ni aran wa, rapa gbe okunrin kan nigbati moto mbe lori ere, o ṣubu sinu moto o si bere si tu ipa. o nwa itọ gburu lẹna.

Igbẹ li a nfẹ ewe, Oko l'a nfẹ ewe'bẹ, gbogbo inu moto daru, awọn elomiran nfi ibẹru bojo bẹ silẹ kuro ninu moto, gbogbo enia nsa ki nwọn ma ṣe tẹ itọ rẹ mọlẹ, ọpọlọpọ awọn enia to fi ibẹru bojo bẹ silẹ ninu ọkọ lo fi ọrun ẹsẹ ṣẹ.

Nwọn gbe ọkunrin oniwarapa na lọ sile alaisan ati awọn ero ti nwọn ja bọ ninu moto ti nwọn fi ẹsẹ rọ. A gbọ wipe derẹba moto na kotele mọ pe nkan ṣẹlẹ ninu moto o si rin jinna diẹ ki o to duro.

## AWON OBINRIN GBOGUN TI KOTU EWOHIMI

A gbo Irohin wipe lasiko ti Oloye Enahoro ti nse baba Tony Enahoro nse idajo ninu Kotu lowo ni ogun awon obinrin ti egberin enia fi binu ro wo inu Kotu wa pelu igo apola ati omori-odo.

Mefa ninu awon obinrin na fi ara sese, nwon si gbe won lo si ile alaisan ni ilu Agbor. Awon obinrin bi mejile-logoji ni a gbo pe awon olopa ramu nipa rogbodiyan na.

Ohun ti a gbo wipe o fa sababi r a a i wipe, awon olopa ibile so fun obinrin kan pe ki o kuro ninu iso kan nibiti a gbe ti ko oja si r, K o wa si oja titun ti nwon sese koko pari tan a gbo pe obinrin na taku wipe on ko ni kuro, ni olopa ba ra obinrin na mu, nwon si mu lo ti mole.

Eyi lo fa ibinu gbogbo awon obinrin oja, ti nwon se di gaga-di gogo ti nwon si lo pa adajo mo ile ejo.

## AKI I B'OBA JA, IRO !

KANO. A gbo irohin wipe, nigbati Alhaji Sir Muhamadu Sanusi, Oba ilu Kano, fi nse ayewo adugbo Sabongeri Kano, ni awon enia kan ti o ko ara won jo bi mejila, dapora si oba Kano nigbati o ngb ojude won koja lo wipe, yegede, obaiyeje, enia lasan, ti o nta gbogbo aiye je.

Nigbati awon olopa sakuru si arin awon enia na, gbogbo won sa ... awon meta ti o je omo ... ninu won ni owo olopa te. Oruko won niwonyi: Illi Fepe Sadiku Fage ati Ibrahim Fage, awon meteta si je omo ilu Kano. Olopa ko gbogbo won lo siwaju adajo fun ... awon fe da ilu ru, nwon fe da ija sile. Nwon so wipe ... ki ba oba jo, iro ni, awon ko bu oba.

Olopa ti ko awon enia na wipe nwon to mejila sugbon awon ... awon enia meta nwonyi ni adajo ... ejo won si ojo Monday 19th October 1959.

# Omo Nigeria Ye Ijoye Si Nilu Oyinbo



Obinrin ti a de du ti a nwo ni apa osi yi ni eniti oruko re nje Grace lati ile Nigeria ti o lo ko ise nilu Oyinbo. Nigbati Ijoye obinrin Oyinbo kan wa be won wo, nibi oja Baso ti nwon si fun iranlowo egbe Omgbagbo o si fi ododo ye si.




AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O. BOX 599. LAGOS.


# Itan Ajapa Ati Ekun

**(Apa II)**

Lati owo Eso.

Nigbati ekun ri pe, oja daru nitoto o wipe kai! Ajapa wi be, o se be, o bo si arin oja, o ko iba eru ti o ni ko. Ajapa paapa bo sile lati ori ope wa, o ko, o nko eru. Nigbati nwon gbe nko eru Ajapa pelu Ekun pade larin oja. Ekun so fun Ajapa wipe Ha! Ajapa, o wibe, o si se be? Ajapa dahun pe, euiti oro yi ba sojn re ni agbari yio ta.

Nigbati oja tuka, nwon kebosi lo ba oba ki o wa gba won kuro lowo Alijannu ti o wo oja. Elomiran so pe, Alijannu na gun, o funfun, elomiran ni o de akete, elomiran ni o yo kondo ati kumo dani elomiran ni gbogbo ara re kiki egun, beni olukuluku enia nso eyiti o wu u oba paapa ko si mo eyiti yio dimu ninu oro na.

Oba wa yan iwon ogoji jagunjagun ti nwon ti ha mora ki nwon tele awon enia lehin lati lo ko eru won wa sile. O si tun se nigbati oja ku ola, Ekun ri Ajapa ti o nkoja lo lojude, o sare lo ba a, o bere wipe, kini ola yio tiri o? O si dahun pe gegebi ti oja to koja lo ni yio ri.

Ni ojo oja, ekun tun lo ba ninu ibuba leti oja. Ekun wa nso Ajapa lati mo igbati yio koja si oja. Ajapa ko sinu iho ile re o de ori ope, otun bere si korin o si nlu bayi wipe-

Ope jo mi kawo, Jo njo
Ope tagiri takan
Ope ta sasa kaja
Ro ba jo. Oja a mi
Koijo oja ngbon

Ibe ni igi ope arin oja titun njo oja si fo, Ekun tun bo si arin oja, o bere si jeja.

Ajapa sa gbon pupo, gbogbo awon eru ti o ko ni oja ninu iho ti Okete gbe fun lo nfi won pamo si. Nigbati awon enia tun ro giri lo ba oba pe Alijanu na tun de, Oba pe mewa ninu awon emewa re' o ni ki nwon lo pe Ifa wa fun on E ma ka iwe irohin Eleti Ofe, eo gbo bi Ifa ti se da ejo na.

**NIGERIAN RAILWAY CORPORATION**

# LOCAL PASSENGER TRAINS

## 1st. 2nd & 3rd Class

### Lagos-Offa

Departs Lagos at 8 a.m. daily except Sundays arriving at Offa 7.55 p.m. On Sundays this train runs to Ibadan only, arrived there at 3.15 p.m. (Canteen Cars provided).

### Offa-Lagos

Departs Offa daily except Sundays at 7.50 a.m. arriving at Lagos at 8.0 p.m. On Sundays this train departs from Ibadan at 1.20 p.m. arriving at Lagos at 9.0 p.m. (Canteen Cars provided).

### Ibadan-Offa

Departs Ibadan 6 a.m. arriving at Offa 11.20 daily.

### Offa-Ibadan

Departs Offa 1.40 p.m. arriving at Ibadan 7.0 p.m. daily.

**The Best Way is the Railway**

RAILTRAVEL IS
- CHEAPER
- SAFER
- BETTER

# Awon To Lo Kose Ero Isoro



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn ọmọ akẹkọ meta ti o wa lati orisirisi ilu lati wa kọ iṣẹ orisirisi ọna ti ema ngba fi sọrọ sinu ẹrọ gbohungbohun. Orukọ wọn niwọnyi :- Ismaila Bin Alang, A. Achebẹ ati omidan Mosumdar.

## JAGUDA JALE NI OKUN ALASIA

Okun Alasia. A gbo" irohin wipe gbajumo kan ati omode kekere kan na ese le ghatagan ni Okun Alasia. o ba aso re sile o si fi omo kekere kan sile ki o ma so. Okunrin na fi oreko re nje Abegunrin lo lowe ninu okun.

Nigbati o ti lọ tan ni awọn ọmọ jaguda meji, Muri Mustafa ati Yẹkini Bakare, lo ko aso Abegunrin mole ni omo kekere ti nwon fi so aso na bere si kigbe ole, ole, ole.

Awọn omo jaguda na fekita, nwon si wo inu igbo oro. Iyapa lo ni gbogbo awon enia ba gba ti won lẹhin nwon nun woḥ dọ nwon to de Abule Inupa.

Awon olopa se iwo gbogbo aso ti awon omo Jaguda na ko lowo Ogbeni Abegunrin, o je Poun metala abo (£13.10) Adajo ni ki Mustafa lo si ewon osu mejila ki Bakare paapa l'o si ewon osu mejila.

## ERAN TI NWON PA NI ILU KATSINA

A gbo wipe ise awon eran ti o ngbe ilu ati agbegbe de Katsina te die ni 395,340 gbogbo won ni nwon si ba apa fun nitori arun ilegbona.

Iye awon eran ti nwon pa je nilu Katsina lodun to koja je 92,202. Bi a ti se lele won niyi :-

Awon malu ti nwon pa lodun na je 10,639 awon ewurẹ tabi eware je 4,103 gbogbo eran nwonyi ni nwon paje.

Nitori ti ni nwon la [illegible] omiiya, inya ati kiliya.

Kere o!

A ni orisirisi ogun German to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS MEDICINE STORES
7, Egerton Road Lagos

# Nigerian Ports Authority

ELECTION OF MEMBERS TO REPRESENT THE PAYERS OF SHIPS' DUES AND THE PAYERS OF HARBOUR DUES HELD ON THE 22nd DAY OF SEPTEMBER, 1959

**NOTICE IS HEREBY GIVEN that in accordance with the provisions of the Nigerian Ports Authority (Election) Regulations 1956 the under mentioned candidates have this day been duly elected as Members of the Authority to represent the payers of ships' dues and the payers of harbour dues.**

MEMBERS TO REPRESENT THE PAYERS OF SHIPS' DUES

**Hon R. H. CHALCROFT, M. H. R**
**Chief S. L. EDU**
**Hon E. C. W. HOWARD O.B.E., M.H.R**

MEMBERS TO REPRESENT THE PAYERS OF HARBOUR DUES

**Mr W. G. DUNCAN**
**Mr D. A. MACLEOD**
**Mr M. A. K. SHONOWO**

A. R. CORDON

Secretary To The Authority and Returning Officer

**22nd September, 1959**
**N P A NOTICE No 344**

aworan Oloye Awolowo lara re tabi nile re, aluwodi ni nwon ma lo eni na.

Awon obinrin ti o ntaja fi iberu tuka ni owurọ, nigbati awon olopa de nigbehin, nwon ko ri enikan mu, nwon si ti lo

Omobinrin kan ti o nje Grace Bolaji ti o nta awo so wipe oja ti nwon baje fun on to aladota Ponun, a ti gburo irufe isele be ni ilu Offa siwaju ki nwon to de Ilorin.

## Ejiwunmi Nilu Oyinbo



Iwon adajo enia lo wa silu London fun apero kan pataki nipa ilosiwaju eko ti nwon se ni Oxford, nilu London.

Okan ninu awon asoju ile Nigeria ti o lo fun ajumosepo na ni Ogbeni T. O Ejiwumi ti o je Alabojuto awon ile eko ni agbegbe Iwo-orun. Oyinbo ti o duro ti o mba jewo ni Ogbeni G. L. Loyd, Olotu ile eko ti ilu Oyinbo.

**WINDU SAKKARA'S**
**Religious Art Jewelleries**



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers Kawaches, Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose 4/- Postal order by Air Mail for Catalogues and Literature.*

**WINDU SAKKARA, 431 Archway Road, London, N.6, England**

"The English Association of Accountants & Auditors. The English Association of Estate Agents & Valuers. The English Association of Secretaries. Founded 1941. Membership on Professional Experience (Give Details) or Exams passed. 9, Charles St. Newport, Mon. Eng".

**ARA-O-LIN - IPARA ATATA**




ARA-O-LIN je ipara ti o gbamuse. O tayo gbogbo irufe ... ti o ba l'oja. O dara fun ... ara-latanlatan, ehin-didun, ibaradi-dise, ... tabi sese ro, efori, tutu, otutu-aiya, ... orun-didun ati orisirisi aisan kungekunge ... werewere ti o nta, awon Yoruba npe e ni "ATA". ... ni "OSE" Hausa si npe e ni "BOROKONU". ... (eko l'owo-oko) lati mo bi o ti ri.

**The Egba Trading Aradan Stores,**
**18 Denton Bridge St., P. O. Box 1, ...**

SICK? AFFLICTED? Crippled? Write for free List of Vital Books on Divine Healing, also Helpful Information and Prayer to:- Gordon Cove, Brierley Hill, Staffordshire, England.

## AWON GBE SUNMOMI WA SI ILORIN.

ILORIN. A gbo irohin wipe awon janduko kan ko ... ti wa silu Ilorin, ni asiko ti Dokita Nnamdi Azikwe ti wa ilu na lati wa bere ikede tire, awon omo ... ti nwon ba oko gun'le si Ilorin, gbogbo won lo si ... olu, won bere si je oja kakiri, nwon ba ile je nwon ba moto je, gbogbo eniyan ti nwon ba ti rio ni omo egbe Action Group, alubole ni nwon ma lu e.

Ninu awon enia ti nwon lu na ni Alhaji Mukanda Dindi ti o je Sekiteri Ilorin Talaka Parapo, enikeni ti nwon ba ri

Printed & Published by The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street, P.O. Box 47 Lagos, Phone 23370.